OWE

Kini anse li o k o and'oru, ali A g b ẹ ti yio ji iṣu ẹgbẹrẹ wa.

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.



READY FOR SALE
Iwe Arofọ ti -:
ANỌYIN LOHUN-BI-ỌMỌGE- IMARO
APA KETA
LATI ỌWỌ
G. A. SOWUNMI
Price 2/-
Modupe Press
16, Bamgbose Street,
Postage Extra



VOL. II No. 55 WEDNESDAY JULY 16, — JULY 23 1958 KỌBỌ KAN (1d)


# Adota Koboko San ju ponun Mewa lo

Abeokuta

Hausa kan ni awon olopa ramu ti nwon si fi sun esun wipe, o nyo awon ero ti o ba nkoja lenu ati pe nigbati awon olopa fe mu, o ba won ja.

Bi ọrọ na ti lọ ni yi:— A gbọ pe ọkunrin Hausa na ti o njẹ Yaro a ma ju oko, igo ati Ogulutu ba ẹnikẹni ti o ba k ọ j a ni opopo Lafẹnwa. Nigbati irohin de eti awọn ọlọpa o fi Ala- nwọn ranṣẹ lọ mu Hausa na, ṣugbọn o tun ba awọn ọlọpa wọya ija. Nigbẹhin awọn ọlọpa ki i mọlẹ, nwọn si gbe duro niwaju adajọ.

Ọkunrin na rojọ, o si jẹbi niwaju Adajọ na, o ni ki Yaro, Hausa na s a n ponun mẹwa (£10). Bẹni ọkunrin na ba fo soke, o wipe ponun m ẹ w a tabi kinla! jẹki nwọn na mi ni adọta koboko dipo, nitori nko ni adọjọ kọbọ lọwọ.

Adajọ fesi wipe kotu mi ko nṣe ti Alkali, ni iwọn igbati o ko le ri ponun mẹwa san, ki o lọ si ẹwọn oṣu kan. Hausa na sọ fun Adajọ w i p e Cognac Martell ti on mu nigba owurọ lo nse loju kan, kan, kan ni ko jẹki on mọ nkan ti on n ṣ e, on ko le ri ponun mẹwa san.

Adajọ fọhun wipe, nigbati o ko ni owo lọwọ e ṣe ti o fi nmu ọti olowo? ati pe o ko mu ọti na mọ niwon, o nmu de ipo ti o fi nṣe pala-pala ti o si sena fun gbogbo enia lati koja ni oju ona ti ijoba la silẹ.

Nje bi ko ba fi ri ponun mẹwa (£10), ki o lo gbẹwa oṣu kan, a ko nna enia nihin, nitori ko nṣe kotu Alikali.

## Omo kan sonu ni ilu Zaria, a ri he ni Abeokuta

IJẸBU ODE

Obinrin Adelebọ kan ti o nje Sala ati ọkunrin kan ti o njẹ Sule ni awọn Ọlọpa nba ṣe ẹjọ ni Ijẹbu-Ode fun ẹsun wipe nwọn ji ọmọ gbe.

Bi ọrọ na ti lọ niyi:— Ni [illegible] un 1951, nilu Zaria, ọmọde kunrin kekere kan ti orukọ rẹ njẹ Sikiru Lawal ngbe ọdọ ẹnikan ti awọn obi rẹ fi si, ẹni na ni Ọgbẹni Bakare nqu Zaria nitori ki o le ri aye lati ma ba [illegible] rẹ lo, iṣẹ si ti gbe baba ọmọ na lọ si idale, iya rẹ ti ku ni ọdun 1949.

Salamọtu lọ sọdọ awọn ti o nṣe itọju ọmọ na, o fi ara rẹ han gẹgẹbi ẹgbọn baba ọmọ na, o fun ọmọ na ni oriṣiriṣi nkan. Nigbati o ṣe ni Sala tun de o ni ki nwọn jeki ọmọ na sin on lọ si Teṣọn Reluwe (Railway Station), alọ ni nwọn ri, nwọn ko ri abọ ọmọ na.

Ibẹ ni nwọn ti mu irohin lọ fun Ọlọpa, ti nwọn si ti bẹrẹ si wa ọmọ na. Ṣamọ-ṣamọ, nigbati Salamọtu mu ọmọ na de Teṣọn Reluwe, nṣe lo gbe wọkọ, o si mu wa si Ijẹbu-Ode o wa fan si ọdọ Sule apanisile.

Nigbati ọrọ ni mimọ fun Sule wipe awọn Ọlọpa nṣọdẹ rẹ nitori ọmọ ti o gba sọdọ, kia mọsa, o yara mu ọmọde na kọri si Abẹokuta, o si fi sọjọ si ọdọ ọkunrin kan ti o njẹ Abudu. Lọdọ Abudu yi ni awọn Ọlọpa ti ri ọmọ na he ni eṣi.

Nisisiyi ọmọ ti a wi yi Sikiru Lawal ti dagba to ọdun mejidinlogun, o si mbẹ ni kotu na ti o nfi eti ara rẹ gbọ ohun ti o ṣẹlẹ lori rẹ ti on alara ko mọ. Ẹjọ yi koiti pari, iyoku ẹjọ na di ọjọ kẹfa oṣu kẹjọ ọdun yi, 6th August 1958 niwaju Desalu ni Ijẹbu Ode, ẹ o ma gbọ bi nwọn ba ti pari rẹ si.

## EWON ODUNKAN FUN SUBUOLA ABIOLA

Ilesha, Monday

Ni ọjọ aje ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni Ṣubuọla fi ara rẹ han niwaju adajọ agba Ọgbẹni Falode Baba ẹgbẹ Ilesha ti kotu Ibilẹ fun ẹsun owo gbigbe arabinrin Ṣubuọla to ngbe Ọmọfẹ Street ti ọjọ ori rẹ jẹ marundinlogoji (35) sun ẹkun kikoro ni iwaju adajọ agba na.

Ṣubuọla jẹbi wipe on ji pọun mẹtaleladọrun ati ṣile mẹta o le tọrọ pẹlu epini ti iṣe owo Emily. Adajo si fi odaran yi si ẹwọn odunkan. [illegible]

## Awon to se omo rere gba iyi ni University Ile America



AWỌN ti a nwo ninu aworan yi ni awọn ọmọ ilẹ Amẹrika to se daradara ti nwọn si gba oye ile ẹ k ọ University lati ile ẹkọ giga ti nwọn npe ni Roosevelt High School.

Orukọ wọn niwọnyi:- Bẹrẹ lati ọ w ọ osi, Bonnie Benson, E. T. Benson, on ni baba ti o bi Bonnie Benson ati ẹni kẹta wọn ni Harry Johnson.

Nigbati Ọgbẹni Benson fi nsọrọ nibiti nwọn gbe ṣe awuye-wuye iyẹsi ti oye ti a fun awọn ọmọ mejeji wọnyi, o sọ pe, ẹ jẹ ki a ni igbagbọ si Ọlọrun ati lẹhin iṣẹ wa si i, ẹ jẹki a ranti pe a niṣẹ lati ṣe fun ilu wa, ki a si ṣikọ ọmọnikeji wa bi a ti nfẹ ki nwọn ṣe si wa pẹlu.

# BABA OLOMO META

O BẸRẸ LATI ỌSẸ TO KỌJA

NIGBATI wọn de odo yi, wọn ri ati wọ odo b a b a wọn, ṣugbọn wọn ko ri ati jade, nigbana ni gbogbo wọn ba bọra silẹ, wọn wa ni iṣẹ kan mudomudo boya nkankan fa baba wọ odo lọ ni.

Ni mudomudo ba ki ẹnu bọ odo yi, on fa fin! fin!! fin!!!, odo yi fi gbẹ patapata, o wa ku asan ẹrọfọ.

Nigbana ni wọn ni iṣẹ kan Mẹrẹmẹrẹ, mẹrẹmẹrẹ ba fi ẹnu le ẹrẹ yi, onfa fin! fin!! fin!!! ẹrẹ yi gbẹ patapata, o kan a p a t a. iho kan wa ni abẹ apata yi, iho na pọ obu aya, nigbana ni iṣẹ wa kan lakutalakuta na basi bọra silẹ obẹrẹ si la okuta yi titití, o la tan, nigbana ni wọn wa kan ẹja nla kan.

Ẹru ẹja na pọ to bẹ gẹẹ gbogbo wọn wa sọpe ha! ha!! ha!!! eja lo tobi bayi laiye. Nigbana ni nwọn ba mu ada lati fi la ẹja yi ni inu (ikun), bi wọn ti fi ada si ẹja yi ni ikun, bẹni baba wọn ni idodo mi ni yeno inu wọn dun, wọn tun fi ada si ẹja yi ni ọrun, baba wọn tun kegbe pe aya mi ni yen o.

Gbogbo wọn wa ro gẹgẹ bi baba wọn yi yio tise jade kuro ninu ẹja nla yi, ọkan ninu wọn wa ni ẹ jẹ kia fa yọ lati ẹnu rẹ yi, gbogbo wọn si sasaro gẹgẹbi wọn yio tise gba ẹja yi niu, ẹnikan ba fa ni ijagbọn kan ekeji na si tun fa ni ekeji na pẹlu.

Ki ma fa ọrọ gun titi, ni wọn ba gba baba kuro lẹnu ẹja nla yio. Nigbati wọn wa de ile, baba wọn ko ọrọ o sọ fun awọn ara ile, awọn ọmọ na tun ko wọn ro gẹgẹ bi wahala wọn na ti to.

Lati Ọwọ: —
Y. ADE. BURAIMOH,
Ọmọ Ọtun-Oro.

Ẹjọwọ ẹnyin onkawe wa aladun oloyin mọmọ yi.

TANI O WA YE KI BABA YI FẸRAN JU NINU AWỌN MẸTẸTA YI

Ẹ o si tun ma gbọ itan miran lagbara Ọlọrun, ẹmi gigun fun gbogbo wa amin

Modupẹ aye ti ẹ gbami Ọlotu abimọ-lemọ lekute ile.

# Ilu Alaska di ara ile United States of Amerika

ALASKA

OJỌ ti pẹ ti apa ilẹ oke ilẹ Alaska ti nfẹ fi ara mọ awọn ilu Amẹrika ti nwọn fi ọwọ so ọwọ po.

Ohun ti o wa ku ki nkan na to lẹsẹsẹ ni wipe, nwọn nfẹ ki awọn ara ilẹ Alaska na fi ẹnu wọn sọ jade kini nwọn ri ki nwọn to faramọ lati papọ pẹlu U.S. A. a si lero pe gbogbo wọn ni yio sọ pe nwọn fẹ.

Lọjọ 30th osu Jnue 1958 ni igbimọ Senate fi ara mọ wipe ki ilu Alaska di ara kana ati alabaṣe po U.S.A. Gomina ilu Alaska, nse lo joko jẹjẹ ninu ile igbimọ nigbati nwọn fi ndibo enia mọrinlelọgọta to fẹ bẹ, ogun enia ni ko fẹ, Gomina na kigbe wipe on dupẹ lọwọ Ọlọrun nigbati igbimọ faramọ wipe ki ilu Alaska di ara kanna ati ọmọ iya kanna pọ pẹlu U.S.A.

Nigbayi ni ilu Alaska yio di ilu pataki lori ilẹ Amẹrika.

Nigbati o ba di ni ibẹrẹ ọdun 1959, ni awon igbimọ mejeji ti nwon o yan ninu ilu Alaska ati ẹnikan ninu igbimọ Representative yio pejọ papọ pẹlu awọn igbimọ United State.

AKIYESI

Eniti o ba fẹ ra IROHIN IMỌLẸ ni Ọtun-Oro, ki o lọ si ọdọ AṢOJU wa ti oruko rẹ njẹ Charles Bojuwoye Toju iwarẹ Bookshop lẹba Market Street Ọtun - Oro

No. 89

**Inland Waterways Department**

## NOTICE NO. 7 OF 1958

SAPELE — BENIN FERRY SERVICE

It is notified for general information that due to the annual overhauls of t h e craft operating this ferry, a reduced service will be maintained from dawn to dusk by one vessel only until about the 23rd July 1958.

C. ATKINSON
DIRECTOR
*Inland Waterways Department.*


## Iwe Egbogi Ajebidan




Iye owo 20/- pere. Fi owo ati 1/- stamp ranṣẹ si Popular Bookshop, c/o Post Office. Ebute-Mẹtta.


# LAKAYE NI BABA OGBON

NI igba lailai ti aisedede ọmọ-enia ko iti pọ, ti enia, ẹranko ejo ati ẹiyẹ ti ngbọ ede ara wọn, ti nwọn si jumọ nsọrọ pọ, ọgbọn ati lakaye jọ ọrẹ, wọle wọde ara. Ni igba pupọ ni nwọn ama jọ damọran pọ, nwọn asi ma gba ara ni iyanju ninu ohun pupọ.

Ọrẹ wọnyi dun tobẹ gẹẹ ti awọn enia nro pe boya o ni asiri kan ti o wa larin wọn.

Ṣugbọn ni irọlẹ atura ọjọ kan bayi, ọgbọn ati lakaye jọ nsere ni ojude. Nibiti wọn ti nsọrọ lori awọn orisirisi ẹda ati nkan miran, ni wọn ba de ori koko ọrọ kan, ọgbọn dahun pe bi wọn tilẹ jọ nsere ọrọ meji o yẹ ki lakaye le mọ pe on ọgbọn ni agba, lakaye ya ẹnu silẹ o fẹrẹ ma le pa de, o wa sọ fun ọgbọ pe asiwi niyẹn. ati pe ki o tu itọ rẹ danu, ki o mọ daju pe on lakaye ni agba, ati pe aye baba ni on wa fun ọgbọn Eyi mu ariyanjiyan wa ni ọjọ na.

Lakaye wa mu wa ni imọran pe ki awọn mejeji wa se idanwo lati pinnu ẹniti o jafara ju, imọran yi na tẹ ọgbọn lọrun o si gba bẹ, nwọn wa fi ọjọ si arọ ọjọ keji, ohun ti wọn si fi eto le lori ni pe lakaye yio gbe ẹwu-nla aṣọ ẹ t u kan fun ọgbọn ki o lọ ta ni ilu awọn arẹwa ẹ i y ẹ ti anpe ni lekeleke.

Ni kutukutu ọjọ keji lakaye gbe ẹwu ẹtu alabara yi fun ọgbọn, o si mu ọna rẹ pọn bẹ gẹgẹ. o di ilu awọn ẹiyẹ lekeleke, bi o ti de'bẹ o patẹ ẹwu ẹ t u yi kalẹ, awọn si na ni orisirisi iye owo, nikẹhin ọkan ninu nwọn ra ẹwu yi ni ọkẹ meji (eyiti nse iyebiye owo nigba ti wọn) o sọ fun ọgbọn pe on yio lọ fi han awọn ara on lati mọ bi o ba to iye owo yen, bi bẹ kọ.

Ọgbọn gba bẹ fun sugbọn alọ ni ọgbọn ri kọ ri abọ rẹ mọ, gbogbo awọn ẹiyẹ wọnyi ni wọn jọ ara wọn tobẹ ti o jẹ pe eyikeyi ti o ba ti ri ninu wọn li o nbere owo aṣọ yi lọwọ re. Iyẹn na asi sọ fun pe on ko ra nkan bẹ rara.

KO I 'TI PARI.

